# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJO.

VOL. NO 815 LAGOS SATURDAY APRIL 14. — APRIL 20, 1962. KỌBỌ MEJI (2D)


# Baba Kan Fi Omo-bibi Inu Re D'agbo, Eyi Ara !

AKURẸ — 'Ni ana ọjọ Jimọ ni awọn ọga ọlọpa ni Ibadan da awọn ọtẹlẹmuyẹn, Ọlọpa'nu wọn si agbegbe Ekiti lati maa wa baba agbẹ kan ti orukọ rẹ njẹ Ajibuwa Ọshọ, ara Ipoti lẹba Akurẹ, ti o fi ọmọbibi inu rẹ d'agbo kakiri.

Onirohin wa sọ wipe lọjọ Aiku (Sunday) ti o kọja yi ni o ni ki ọmọ on na, ti orukọ rẹ njẹ Ademọla, ba on kalọ si oko. Nigbati o di aṣale ti o pada wa silẹ, ko mu ọmọ na bọ wale, o ni on fi sile pẹlu ẹnikan ti o mba a ṣere.

Iya ọmọ na sọ wipe nibiti awọn gbe nwa ọmọ na kiri ni awọn ri ori rẹ ninu ikoko agbo-tutu kan ni ideko baba agbẹ na, ati awọn ẹran ara ọmọ na ti o ge kulu - kulu; awọn tun ri ori awọn enia meji miran nibẹ pẹlu.

Iyawo mẹrin ni baba agbẹ na ni, iya Ademọla ti o fi d'agbo yi ni afẹgbẹhin patapata, ọmọ kanna ti yio si bi fun un niyi.

Ọwọ ọlọpa koiti tẹ bi a ti nkọ irohin yi lọwọ.

## Ọmọ Ẹgbẹ Ilorin Talaka Parapọ

ILỌRIN—Irohin kan ti a ri gbọ ni ọjọ Alamisi ti o kọja yi wipe aṣoju ọmọ Igbomina ninu Ile Igbimọ Apapọṣe fun Ilẹ Nigeria, Ọgbẹni P. B. Ọlatunde, fi ọdọ awọn ọmọ Ẹgbẹ Ọlọpẹ ti o wa ni Ile Igbimọ na sile, o bọ si ọdọ awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi, o ya ọpọlọpọ awọn ẹgbẹ ọdọmọde oṣelu Ilọrin lẹnu, ṣugbọn ọrọ na ko jẹ iyalẹnu rara fun awọn agba-ilu ti o mọ idi rẹ.

Gbarà ti irohin na ti tanka arin ilu ni onirohin Eleti—Ọfẹ ti nfi'mu le'ko kakiri Ilọrin, onirohin wa na si fi wosika ṣọwọ si wa l'oru ana pe ẹka ẹgbẹ awọn ọdọmọdekunrin ẹgbẹ Olomi, (N.P.C) ni Ilọrin ti tun ṣe ipade lati jiroro nipa ọrọ ipinlẹ Igbomina ti o ti wa nilẹ.

Nwọn sọ wipe awọn fura si ọrọ Ọgbẹni Ọlatunde, pe ọrọ ti a nfi ẹgbẹ Ọlọpẹ silẹ na jẹmọ rogbodiyan ọrọ a-pinlẹ-a-ko-pinlẹ tabi ọrọ a fẹ ya igbimọ si meji ti o ti wa nilẹ.

Ki a sọ gasikiya, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Talaka-Parapọ dapọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (Ọlọpẹ) ti mo de ọdọ wọn ni nwọn kọ lati sọrọ.

(Wo yoku loju ewe keji)


## Lagos Citizens' Right Protection Council

There will be a

MASS MEETING OF THE ABOVE COUNCIL

on Monday 16th April 1962

at

THE CORONA CINEMA, LAGOS

Alli Street

at 5.30 p.m.

Speakers :
Chief T.A. Doherty
Chief Abudu Smith
Chief T.A Makanju
Messrs Raji Etti, A.T. Ariori
Hadji Oshodi
Hadji Lasisi Ojikutu
and Mrs. Ayo Manuwa.

Subject : The Position of Lagos in Nigerian Politics.

Lagos, The Cradle of Nigeria Nationalism


# Eleti-Ofe D'araba

## Ọmọ Ẹgbe Ilorin Talaka Parapo

( O bẹrẹ loju kini )

Bi mo ti nkọ iwe "wosika" yi lọwọ ni irohin kan kan mi wipe awọn akọwe ibi iṣẹ Ijọba Ilọrin ti ẹda iwe ikilọ ti Ọlọla Ahmọdu Bello, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa fi ṣọwọ lati Kaduna gba, ninu eyiti o wipe ijoye-kijoye, igbimọ-kigbimọ tabi awọn akọwe ile iṣẹ Ijọba tabi adajọ kotu Alikali, ti nwọn ko ba ṣe ẹtọ, iile ni on yio le wọn danu bi ọgan. Nitoripe o to gẹẹ, eyiti nwọn sọ ọrọ buruku si Ijọba ipinlẹ Ariwa na to.

Ọpọlọpọ ẹda iwe ikilọ na ni nwọn si ti fi ran awọn dandoka kakiri ọdọ awọn ijoye ati adajọ Kotu (Alkali) ti nwọn wa labẹ Ilọrin.

Ni Eko, awọn ogunnagbongbo inu ọmọ ẹgbẹ Igbomina mba ipade wọn lọ ni adugbo kan ti a npe ni Ẹnu-Ọwa l'Eko, ni bẹsini awọn ọmọ Ẹgbẹ Ilọrin mba ti nwọn lọ ni Mushin.

Bi iyoku ba si tiri, ẹo ma gbọ lọsẹ ti o mbọ.


Awọn òwò sise tuntun ni ijeri si ilọsiwaju

# UAC

# nran awọn ọmọ Nigeria lọwọ lati di onişowo asiko ati lati da duro fun rawọn

Irinwo-le-ni-egbafa (12,400) ọmọ Nigeria ni U.A.C. ti fun ni anfani ati ra awin ọja ti o le ni ogurin-le-ni egbaa oke poundi (£26,000,000) lọdọdun: awin ọja, imọran, ati ifaramọ ti anwon ẹgbẹ onisowo nfun lọkunrin lobinrin nwọn nran anwon onisẹ na lọwọ lati fọkanbalẹ jere lori iṣẹ nwọn.

THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED


## Alo o! Alo!

1 Ojo pa Olukọrun ... Ọmọba.

2 A ke lori, ake nidi, ... on yio ṣe oro i'le Baba ...

3 Agbalagba ole, Ogb... eegun o di ni ọkẹ, ...

4 Ọna kan wa ni o... babaluwa mi lailai ... kan lode babaluwa ... lailai ara aiye ki ... ero ọrun ki igba, ojo... mọ ni ma ndan,

5 O gba'le gb'ọna, o w... kọrọ joko

6 Ko ṣẹmi ko ojojum... romi, ni mo ngba laiya...

7 O na ketepe, o di ke... tepe o lọ ba wọn ... ọja ketepe.

8 Ikan ni on lo ku sin... igbo, Ikan ni on a f... ẹsẹ ara on rin ... ọrun, Ikan ni ... arin bi afẹfẹ, (mẹ... la npa, (mẹta la nja...

9 A rubọ loke odo, ... fẹ ehin kankan.

10 A ni ki o şişẹ, o şiş... ani ki o s'nmi o nsunk...

## Oko Sa Iyawo P...

Arigidi—Obinrin olulek... kan ti orukọ rẹ njẹ Mar... ni ọkọ rẹ şani aşapa nib... ti o gbe njẹun nitorip... ko loyun ko si bimọ.

Ọkunrin na sọ fu... awọn Ọlọpa wipe ti f... Mary to ọdun mẹfa ... koitu bimọ, on ko si ... gbe agan obinrin dan... On ti şe işẹ ọwọ o... ohunkohun ti nwọn b... fẹ ni ki nwọn şe.

**Ẹpolowo Oja... Yin Sinu Iwe... Irohin Eleti-Ofe...**

## Omobinrin Ilu Saro Nkose Itoju Alaisan



Ọmidan Winifred M'carthy, ọmọ ilu Saro ti a nwo ninu aworan rẹ lọwọ ọtun yi ti ọga rẹ Sister Muriel Dixon, ọga Olukọ ile ikọṣẹ itọju alaisan ailu Oyinbo nfi bi a ti npese ohun elo fun awọn alaisan han-en yi.

Omidan Winifred fẹrẹ pari ọsẹ mẹwa ti o fi npese ara rẹ silẹ lati bẹrẹ iṣẹ Olutọju awọn alaisan ni kikọ fun ọdun mẹta ti yio fi gboye iṣẹ itọju awọn alaisan.

## Owo Olopa Te Adamodi "Omo Balewa"

Calabar—Laipẹ yi ni ọwọ awọn ọlọpa tẹ ọdọmọdekunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Erid Moma, ti o purọ wipe ọmọbibi inu Alhaji Tafawa Balewa ni on nṣe.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa mba ọdaran na ro ni wipe, o lọ si ọdọ ọkunrin onisowo kan ti o njẹ Felix Obiajulu, o ni on le ba a ṣe ki awọn Alakoso Ijọba Apapọ Nigeria gbe iṣẹ kọntrati ti yio fa ẹgbamẹrinlelogun pọnun (£48,000) wa fun. Ọdaran yi fọwọ sọ'ya wipe baba on lo wa nibẹ loni.

Awọn ọlọpa ni ọdaran na tun gbojugbaya, o tun lọ gbe ile ti nwọn nfi awọn alejo-ọlọla wọsi laisi epinni ọlọnini lọwọ rẹ tiyio san fun gbigbe ti o ngbe ibẹ

Nwọn ti fi ipari riro ẹjọ rẹ na si igba miran.


## Wanted

Used Postage Stamps

We would greatly appreciate any used postage stamps that the readers of "Eleti-Ọfẹ" can afford to donate to a Charitable Housing Association.

We are collecting used postage stamps to raise funds to help aged people of limited means from housing difficulties.

Our Registered Office :-

245, UXBRIDGE ROAD,
RICKMANSWORTH, HERTS.,
ENGLAND.


# OKUNRIN KAN KU SI SOSI AGUDA

ONITSHA - Laipẹ yi ni ọkunrin onigbagbọ kan ti orukọ rẹ njẹ Innocent Okoli, ẹni ọgbọn ọdun, fo ṣanlẹ ti o ku patapata niwaju Alufa Padi ti o fẹ gbe onjẹ alẹ Oluwa lọwọ rẹ.

Onirohin wa ni Okoli lọ si Ṣọṣi Aguda ti nwọn npe ni Sacred Heart Catholic Church, lọjọ ti nkan yi ṣẹlẹ lati ba nwọn jọsin, nigbati o de ibẹ, o kunlẹ o ngbadura. Nigbati akoko to lati gba onjẹ-alẹ Oluwa, on na si sunmọ ọdọ Alufa Padi, Rev. Father S. Cloonam, ti o nṣe eto isin na, niwaju rẹ ni o ku si.

Iyanu ni ọrọ na jẹ fun gbogbo awọn ti o wa si Ṣọṣi na, nwọn si da isin ọjọ na duro lati sin oku rẹ.

## Enyin Omo Ile Eko E Fi Oju Si Iwe Yin

Lati ọwọ:- Latif Babalọla

Mo ki gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Eleti - Ọfẹ jake-jado ilẹ Nigeria, ẹ ku inawo ọsọsẹ, ko ni tan nibiti ẹ ti nmu. Oluwa ko ni da ọpọlọ yin ru, mo si tun ki Olotu na iwaju ni ẹo ma lọ o,

(Wo yoku loju ewe kẹfa)


# E ma Ka Iwe Irohn Eleti-Ofe

Losose Fun Irohin Aladun

# ELETI--OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
28, Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI ỌFẸ," LAGOS.
P. O. Box 467 Phone 23370.
VOL XIV. No. 815. SATURDAY APRIL 14 - APRIL 20, 1962


# Enia Kika Fe Bere

Enia kika yio bẹrẹ jakejado ilẹ Nigeria, ninu oṣu May ọdun yi, aṣa enia kika yi jẹ ohun ti o ti wa lọjọ pipẹ, ti ijọba maa nṣe lati fi mọ bi enia ti pọ to nilu kọkan awọn ilu ti o ba wa labẹ ijọba eyi ti o njẹki ijọba leni ifọwọsọ'ya pe iye enia bayi ni o mbẹ ninu awọn ilu bayi-bayi.

Ni ọdun mẹwa-mẹwa ni nwọn maa nṣe ika'nia awọn ilu tẹlẹtẹlẹ, o si jẹ ohun ti o nṣe anfani fun ijọba lati mọ iye enia ti o tọ ki o jẹ aṣoju fun awọn ilu bẹ ninu Igbimọ ibilẹ ati Igbimọ Aṣofin ti o nṣe Ijọba ilu.

Enia kika yi ko'kan owo ori tabi owo ode ti ara ilu nilati san rara, nitoripe t'ọmọ-ọwọ t'ọmọ-ẹsẹ, t'ọkunrin t'obinrin, t'ọmọde ati agba ni nwọn yio ka. Kosi ibẹru nibẹ rara, nitorina, a fi wo'ika wa ọsẹ yi kesi ẹnyin enia wa ki ẹ ṣe iranlọwọ fun awọn onisẹ aka'nia fun iṣẹ idagbasoke ilu wa.

## E Ma Se Fomi Sere




E kilo fun awon Omo yin

# Iwe Si Olotu

## E kede Enia Kika Kiri

Olotu,

Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi laye ninu iwe irohin nyin ninu iwe irohin nyin lati kesi awọn Olotu Ijọba'ipinlẹ Iwọ-orun, ki nw.n jọ wọ ki nwọn gbe moto ti nwọn fi nkede kiri lati lọ si igberiko lati lọ ṣe ikede anfani ti o wa ninu enia-kika fun awọn ara wa ti o ngbe oko.

Oğunlọgọ awọn enia nwọnyi ni ko mọ iwe ka, nwọn ko si tun mọ bi nkan si ti nlọ si nilu. Bi a ba le tete ṣe ikede yi jake-jado fun awọn enia wa, yio mu ki iṣẹ awọn enia wa ti yio ka awọn enia na lọ deede.

Ọkọ ọba ko ni ... nyin lẹsẹ o.

Emi ni

Eko, O. ỌNATADE

## E gba Wa, Owo yi Po

Olotu,

A fi tẹdun-tẹdun kesi nyin, ẹnyin oniwe irohin wa ati ẹnyin oṣelu wa, ẹ ba wa kesi awọn alabojuto Ijọba wa ki nwọn ye bu owo'bode le ori awọn oja ti a nra lọdọdun. Nitoripe bi nwọn ti nbu owo'bode ni ibukubu le ori awọn ọja yi, awa talaka ilu ni nwọn npa lara.

Lati igbati nwọn ti bu owo diẹ lori epo moto ni awọn onimoto paapa ti bu owo lori ero moto kọkan. Ẹnyin na kuku mọ aṣeju iwa awọn enia wa, ibiti nwọn ba sọ wipe ki nwọn fi kọbọ kan si, ṣile kan ni nwọn yio bu si i.

Ẹ gba wa, inira ti owo'bode ojojumọ yi pọ.

Emi ni

Agege J. AJALA

## Iya Oloja, E se Pele

Olotu,

Ẹ jọwọ ẹ ba wa ṣe ikilọ fun awọn obinrin ọlọja ki nwọn ye bu owo ni ibukubu si awọn ọja ti nwọn nta. Lati ọjọ ti nwọn ti gbọ wipe awọn Olotu Ijọba Apapọ Nigeria ti fi owo'bode kun diẹ ninu awọn ọja ti o nti ilu Oyinbo wa, ni awọn ọlọja nwọnyi ti bu owo gọbọyi leri ọja ti wọn na.

Ẹran-namọ ko ṣe ra ni ọja Mọkọla, bẹni owo elubọ nle wa sa ni ọja Dugbẹ, ẹfọ gbure oni sisi ko to ti bọ imu ni ọja Gẹgẹ l'ode ti oni yi.

O dabi ẹnipe awa paapa ni a fẹran lati ma wa inira fun ara wa. Ẹ ba wa bẹ awọn iya ọlọja nwọnyi ki nwọn ṣe pẹlẹ.

Emi ni

Ibadan. O. Ayiki

# Nihin, Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## EKO GB'OLE, O GB'ỌLẸ

Ayiluka tun de o. O to iwọn ọdun melo kan si igbati a wa yi, ti ọmọ baba wa, Ọlaiya ni ita Tinubu l'Eko ṣẹṣẹ ti ilu Calabar de, ti o da orin "Eko gb'ole o gbọlẹ" silẹ. Nkankan ni o dun mi ninu orin rẹ na, iyẹn ni wipe ko fi "o gba oni-wayo Apapa-Ajegunlẹ" sii. Bẹni ni ijẹta ode yi, bi mo ti nlọ ni ita Balogun l'Eko, ni agbero mọto kan ni ki nwa wọkọ on lọ si Apapa Ajegunlẹ.

Ọrọ ti o dun mọ mi l'eti nl o fi npolowo fun awọn ero na b a y i, "B urada, ẹ kalọ Ajegunlẹ, Ajegunlẹ ilu awọn obinrin ti ko l'ọkọ, ilu ọkunrin ti ko laya, ilu ogogoro, ilu wayo" Nitotọ, ilu wayo orişirişi ni Ajegunlẹ; l'ọjọ ti mo de ibẹ ni mo ri ọkunrin Isobo kan ti o fi ọmọ-ọlọmọ di gbese owo ata ati iyọ ti o ra lọja. Lọjọ ti mode ibẹ ni mo ri ẹniti o di akisa sinu agolo panu ti o pe ni siga, ti o si ta fun obinrin alatuta kan. Ibẹ ni nwọn ti nta ọti ogogoro ni hotẹli ti nwọn npe ni wisiki.

### IKU D'ORO

A nu ṣe mi pupọ lati gbọ iku anti wa, Fredricka Rita Ẹkundayọ Dove, Olotu ile-iwe kan ti a npe ni Ladi-Lak Institute ni Yaba, ẹniti o di ọmọ ọdun mejidinlọgọta ki o to ku lọsẹ ti o kọja yi. Boya ọpọlọpọ nyin ko mọ ẹni-kosi na; emi Ayiluka yio f'ẹnu kan diẹ ninu ọrọ arabinrin na fun yin.

Anti Rita jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ti a bi si Saro (Sierra Leone). Ibẹ ni a gbe ti tọ ọ; o ka iwe jinna, o si lọ si ilu Oyinbo nigbati ilu Oyinbo lilọ niyi, a si sin-in fọkọ ni igbeyawo alarede ti o dun jọjọ. Orukọ ọkọ rẹ ni Lọya Akajẹ-Macaulay, o si la ọkọ na jiya pupọ.

Ni iwọn nkan bi ọdun mọkanlelọgbọn sẹhin, a r a b i n r i n na pẹlu ọmọ-bibi-inu Ologbe Lọya J. Egerton-Shyngle kan ti a npe ni Gertrude, nwọn a ma ko emi Ayiluka jẹ ati diẹ ninu awọn ọrẹ mi, awọn bi Ọgbẹni A. K. Disu a k ọ w e Gomina-agba nisisiyi, bi Ọgbẹni Wahab Agunbiade, akọwe 'Bode-agba ile Işẹ G. B.-Ollivant ri. Iyẹn ti a ba lọ ka'we nibiti nwọn gbe nşişẹ ni ile-ikawe ti a npe ni Tom Jones' Memorial Library, l'Ẹhin-Ọgba l'Eko. Ọrẹ mi, ibiti mo nsọrọ rẹ yi ti di ile itaja fun awọn KỌRA ati diẹ ninu awọn "Ọmọ meji-da-owo-silẹ" nisisiyi. Ologbe n a si fẹran Kiriyo ati Imale.

Rita Ẹkundayọ, bi o ba de ọrun ki o şe ọrun're. K i o ma j'ọkun, ki o maşe jẹ ekolo, ohun ti wọn ba nje lajule ọrun ni ki o ma ba wọn jẹ.

Ọmọ oni Saro, ọmọ Aje;<br>
Ọmọ Mojolokun, mo bu omi okun mu;<br>
Ọmọ mo jo lọsa, mo b u omi ọsa wẹ;<br>
Ọmọ mojo laka-nlaka nibiti odo gbe ngbe a w ọ n ojugba mi lọ.<br>
Ọrun re o ! Ọrun re !!

### TIŞA JỌSẸ, O DI GBERE !

Lọju mi, o dabi ẹni wipe olu gboro kunmọ ti Ọgbẹni wa, IKU Alumotu gbe lọwọ lọşu y i, awọn tişa l'onwa kiri. Oni a gbọ wipe ọkan ninu wọn ku ni Ariwa, ọla a gbọ wipe ọkan ninu wọn ku ni Ila-orun, Bi mo ti nkọ iwe yi l ọ w ọ ni nwọn mu ọfọ ọrẹ mi T i ş a Jọşẹ wa fun mi.

R.A.B., ẹniti gbogbo wa mọ ni Tişa Jọsẹ nigba aiye rẹ jẹ enia pẹlẹ, oni suru enia. E m i ko ri ki o binu ri, bẹni ajọ şe işẹ pọ nigbati a nkọwe fun awọn oniwe irohin kan ti nwọn pe ni "Nigerian Mercantile Guardian' l'Eko.

Tişa Jọsẹ, Orun're o !

### ỌDUN ẸLẸGBA

Emi Ayiluka şẹşẹ ti a b u l e Ilogbo ni Ebute - Mẹtta de ni, mo gbọ wipe nwọn ko ni le şe ọdun Ẹlẹgba l'ọd un yi. Ki-lo fa a ? Owo lo fa a. Iyẹn ni wipe Ọba Adele ko ni l e t'ẹşẹ b'omi lọdun yi ? Iyẹn ni wipe iyawo Ayiluka ko ni r i ede ati isan fi pata si ọ k ọ rẹ l'ẹnu ? Iyẹn nipe ko ni si ẹja kuta ọlọra pupọ fun awọn alarede Yaba lọdun ni ? Ọ b a Adele, ẹ la ọrọ na yemi o.

# KEKE ALUPUPU OLOGERE OLOJU-MEJI




E wo ọdọmọbinrin ti o m u kẹkẹ Ologere Alupupu rẹ d'ani pẹlu oju a t u p a nla nla meji ti imọlẹ rẹ ko lẹgbẹ bi nwọn ba tan ni oru, o si le rin adọta buso ni wakati kan.

## Onimoto Kan Fi Egbaa Ponun Tanran Fun Eniti O Palara

ABEOKUTA - Laipẹ yi ni Adajọ Kotu nla kan şe idajọ wipe ki onimọto akẹru kan ti oruko rẹ n j ẹ Amusa Lawal, san ẹgbaa-o-le-meji-dinlọgbọn ponun fun onişowo obi kan ti o njẹ Şunmọla Şotunde, ti mọto akẹru na ge lapa kan n i g b a t o danu lọna Şokoto l'ọdun kẹrin s'ẹhin.

Ninu iwe - ẹjọ ti Şotunde fi pe Ọgbẹni onimọto na l ẹ j ọ si kotu, ẹgbẹdọgbọn ponun (£5,000) ni o ni on fẹ gba fun apa on ti o ge sọnu si Dogo Daji nibiti mọto akẹru na, WJ25, gbe da wọn nu si.

dun on pupọ lati gbọ wipe iyaan nja pupọ ni ilu na, ati pe kinni iru iranlọwọ ti nwọn fẹ ki awọn ara ilu Nigeria ṣe fun wọn nipa ọrọ ti iyaan na.

(Wo yoku loju ewe keje)

# Iya Kan Ro Omo Re Pa

Ondo—Laipẹ yi ni iyawo kekere kan, Janet Oluwọle, ti ko bi ọtaɔ ri, ti Ọlọrun ṣẹṣẹ gbọ adura rẹ, ti o si fun ni ọmọkurin kekere kan, ti orukọ rẹ njẹ Dare, ni a gbọ wipe o rọ ọmọ na ni onjẹ titi, ti o fi rọ ọ pa.

Cnirohin "Eleti-ọfẹ" sọ wipe, ni Agọ Ododibo ni ọrọ na ti ṣẹlẹ, nigbati iya ọmọ na lọ s'ọja ni o ra onjẹ inu agolo ti awọn Oyinbo ṣe sinu panu fun ilera awọn ọmọde.

Iya ọmọ na rọ ni onjẹ yi titi ti inu rẹ fi wu kẹndu ju bi'o ti ni lati ri lọ, iya na si tọwọ bọ lẹnu titi wipe ki o le pọ diẹ silẹ ninu onjẹ na ki o to dakẹ si i lọwọ.

Awọn ọlọpa ti pe iya ọmọ na wipe ki o wa la idi rẹ ye awọn nipa iku ọmọ na.

## Enyin Omo Ile Eko E Fi Oju Si Iwe Nyin

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Lọsẹ to kọja, mo fi itan aladun tẹ yin lọrun, ṣugbọn lọsẹ yi, ọrọ iṣiti ni ngo ba gbogbo ẹnyin ẹlẹgbẹ mi, ọmọ ile ẹkọ sọ, nitorina, mo fẹ ki ẹ fi ara balẹ ka ọrọ na dada, ẹniti o ba si gbọ, ti o si gba bi o ti wu ki o pẹ to[illegible]yio ṣe ni anfani.

(Wo yoku loju ewe keje)


## OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA ỌMIRAN, EYI NI OGUN T' ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA LE FI MA TA

BI IṢU AKARA GBIGBONA.

# E Polowo Oja Nyin

## Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe


## Owolana Becomes Manager

Mr. M. O. Owolana, 35, a member of the staff of Pan Electric Limited, has been promoted to management status. He is now Service Manager in charge of the Radio and Television Repair and Maintenance workshop in Ebute Metta.

Mr. Owolana joined the United Africa Company Limited in 1943. The Company, noticing his keen interest in wireless mechanics, transferred him the following year to U.A.C. Electrical Department.

Mr. Owolana spent nine months in the United Kingdom before returning to Nigeria to take up his appointment as Acting Service Manager with Pan Electric Limited in January of this year.

## Iyaan Onje Mu ni ilu Ajase

Cotonou—Ni aipẹ yi a ri iwe gba lọwọ aṣoju wa ti o wa ni ilu Ajaṣẹ wipe iyaan onjẹ ti bẹrẹsi mu gogo kakiri ilu Ajaṣẹ. Ọpọlọpọ nkan ọgbin ti awọn agbẹ ilu na gbin ni nwọn ti jona bamu-bamu s'oko. Eyi si mu idamu ba awọn ara ilu l'ọmọde l'agba, tobẹgẹẹ ti ọpọlọpọ wọn fẹ fi maa salọ kuro ni ilu na.

Eyi mu ki Olotu Apapọ Ijọba ilẹ Nigeria, Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa, fi ọwọ sọ'ya fun Alakoso Ijọba gbogbo ilu Ajaṣẹ, Ọgbẹni Hubert Maga, pe o

## Proprietor Of Ladi-Lak School Is Dead

Yaba—The death is announced of Miss Fredricka Rita Ẹkundayọ Dove, founder and proprietor of Ladi-Lak School, at the age of 58.

A hard working woman, the late Miss Dove was born in Freetown, Sierra Leone in 1904.

During her life time the deceased founded many institute for the training of our children. She was buried in Lagos on Thursday.

## B B C Interview Nigeria Air Hostesses

LONDON– A little over a quarter of a century ago saw the start of an air Service to West Africa, when planes carried fourteen passengers and the journey took five days. Today, with the new Nigeria Airways and BOAC jet services, the Comet, which can carry nearly 70 passengers, takes 9 1/2 hours.

Two of the Nigeria air hostesses who flew on the recent inaugural flight of Nigeria Airways will be speaking in the BBC programme "Calling Nigeria" on Thursday, April 19, when they will be interviewed about their trip and the sort of training they have had.

Many of the Nigeria Airways staff have received part of their training in Britain. In the past 2 1/2 years BOAC have trained 17 Nigerians stewardesses, who, after their preliminary training in Nigeria, attend a special 8-week course in Britain.

# Enyin Omo Ile Eko, E Fi Oju Si Iwe Yin

(O bẹrẹ loju ewe kẹfa)

Ẹnyin ọmọ ile ẹkọ, ẹ fi oju si iwe yin, ẹ maṣe ya isansa ọmọ, ẹ ma ka iwe yin nile, aiye fijẹ ko dara, ẹ maṣe fi owurọ ṣere, iwọ ti o nlọ si ile ẹkọ giga, ñọ'ju mọ ẹkọ rẹ, fi obinrin lọrun silẹ, jọwọ maṣe ti iwoyi gbe ti obinrin l'ọkan. "Apẹ ko to jẹun ko ni jẹ ibajẹ," ẹ fi ara balẹ ki ẹ kawe yin, ẹkọ jẹ ohun ti o dara, iwe kiṣe ọrọ yẹpẹrẹ, mo bẹ gbogbo ẹnyin ọmọ akẹkọ Nigeria tode oni, ẹ maṣe fi iwe yin ṣere.

Ogun (Heritage) kan ko si ju pe ti awọn obi ba ti ran ọmọ wọn lọ si ile ẹkọ ti o mọ iwe rẹ ti o ba ti jade, ogun tire ni wọn fun yẹn. Maṣe sọ pe Baba ati Iya mi ti ni owo emi koni lọ ile iwe mọ "Agboju le ogun fi ararẹ fun oṣita" toto, o ṣe bi owe, kọ'ju mọ ẹkọ rẹ.

Ẹ maṣe sare ni iyawo, ẹ kọ'ju mọ ẹkọ yin, ẹ ma kawe yin dada, asiko nlọ, ko duro de ẹnikan. Iwọ ti o si pe ara rẹ ni ọmọ jẹjẹ, ti o ko mọ ju pe ki o ma lọ si ode lọ, ti o ma nsa ni ile ẹkọ, jọwọ mo bẹ ọ, lọ jawọ kuro ninu iwa buruku bayi, ko dara ki o si kọju mọ ẹkọ rẹ, suru lo ni aiye, "onisuru lo jọba l'awusa", ẹ lọ ni suru, ki ẹ fi ara balẹ ka iwe nyin.

(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)




# Awo'Rawo

Eyi ni awọn nkan ti yio ṣẹlẹ si ọ nijọsẹ ti o mbọ.

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Ọsẹ yi yio dara fun ọ, bi o ba le fara balẹ ki o ri bi nkan ti nlọ.

PRISCES (Feb 21-Mar 20) Jọwọ maṣe fi oju tinrin enia. Rin mọ enia, gbogbo nkan yio si lọ dede.

ARIES (Mar 21-April 20) Wa ri irohin kan gbọ lati ilu okere ti yio mu owo wa fun ọ.

TAURUS (April 21-May) 20 Ọrẹ rẹ kan yio ṣe iranlọwọ fun ọ lẹnu iṣẹ rẹ.

GEMINI (May 21-June 21) Wa pade ọrẹ tuntun kan lọsẹ yi, nwọn a si san gbese atijọ kan fun ọ.

CANCER (June 22 July 23) Isṣiṣẹ a pọ fun ọ ninu ọsẹ yi. Ma ṣ tẹti si ọrọ awọn alagbọsọ.

LEO (July 24-Aug 22) Ipinnu pataki kan wa ti wa ṣe ninu ile ti o ngbe, ṣugbọn ki o ro jinle ki o to ṣe, ki o ma le mu ipalara fun ọ.

VRIGO (Aug23-Sep 23) Ẹ o dawọle ọrọ iṣẹ kan ti ẹ ti pati ati iṣẹ tuntun kan; iranlọwọ wa nibẹ fun ọ.

LIBRA (Sep 24-Oct 23) Awọn enia pataki kan yio ṣe akiyesi iṣẹ rẹ, wa si ri ẹbun airotẹlẹ kan gba. Wa da iṣẹ rere kan silẹ lọsẹ yi.

SCORPIO ( 24-Nov22) Wa ri iwe kan gba t o fun ọ ni irohin daradara. Ala rẹ yio ṣẹ.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Ti nwọn ba fi iṣẹ kan lọ ọ maṣe kọ ọ, nitoripe iṣẹ na yio sun ọ.

CAPRICORN (Dec 23-Jan21) Wa jẹ ere iṣẹ ọwọ rẹ, iwọ sa maa ṣe rere bi o ti nṣe niṣo. Ere rere mbẹ fun ọ nibẹ.

## Itumo Alo!

1 Ile.
2 Ege
3 Ologbo
4 Aya ọwọ Ọpẹ.
5 Igbalẹ.
6 Ilẹkun.
7 Esinsin
8 Igbẹ, (B), Itọ (C) Iso.
9 Igbado
10 Kanrinkan iwẹ.

## OGA ISE Oniwayo Fese Fe

IBADAN - Laipẹ yi ni awọn Ọlọpa'nu ilu Ibadan fi iwe sode wipe awọn nwa ọkunrin ọga ile iṣẹ kan ti o pe ara rẹ ni M. Bankọle, ti o ṣe ipolowo oruko ẹgbẹ agbẹ kan, United Farmers' Congress, ti on ṣẹṣẹ dasilẹ ninu iwe irohin kakiri, ati pe on si fẹ gba awọn akọwe si ile akọwe ẹgbe na ni S4/44, Elekuro ni Ibadan.

Ọga iṣẹ Oniwayo yi tun sọ ninu iwe ti o fi sode wipe ẹnikẹni ti o ba fẹ ki on gba on l'akọwe si ibi iṣẹ na ni lati fi pọnun mẹdọgbọn dogba, o si gba owo lọ janrẹrẹ lọwọ awọn ti o nwa iṣẹ.

O tilẹ gbọju-gbọ'ya, o kọwe si ẹniti o nwa iṣẹ kan ni Kanọ ti oruko rẹ njẹ Jimọ Ashaolu, ọkan ninu awọn ti o ti gba owo lọwọ rẹ, wipe ki o wa bẹrẹ iṣẹ ati pe pọnun mẹfa ni on a maa san fun-un loṣoṣu. Ashaolu ni nigbati on de ile ti o ni ki on pade on ni Elekuro, nwọn ni nwọn ko mọ ẹniti o njẹ M. Bankọle ati ẹniti o ni apoti'we 3098 l'Oke Mapo ti o nfi iwe si,

Awọn ọlọpa'nu si wa lẹnu nwọn nwa ọkunrin na kiri.

## Alakoso Ijoba Ipinle Iwo-orun Fada Kori Lori Oro Ipinle

Ni ana, nilu Ibadan, Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba ipinlẹ Iwọ-orun daa laba wipe ki Ijọba ipinlẹ na maṣe gba ki nwọn pin ipinlẹ rẹ si meji.

O sọ wipe bi o tilẹ jẹ wipe awọn kan ti da ọrọ na laba ni iwọn nkan bi ọdun mẹfa s'ẹhin, iyẹn ki iṣe wipe Ajọ Igbimọ awọn l'Ọba-lỌba ti fọwọ si, nitorina, ki Ijọba maṣe gba, ẹnyin na yio si ranti wipe ko si eyiti o fẹ ki nwọn pin kuro lara ipinlẹ on ninu awọn Ijọba ipinlẹ yoku.



CHIEF. S. L. AKINTỌLA

## IMPORTANT MASS MEETING

ASSOCIATION OF THE DESCENDANTS OF LAGOS CHIEFS

**and**

**The Lagos Aborigines Society**

**All Lagosians are invited by the Association of the Descendants of Lagos Chiefs and the Lagos Aborigines Society to a Mass Meeting at Enu—Owa Lagos on Sunday the 15th day of April 1962, at 4 p. m.**

### AGENDA :

1. Deposition of Chiefs Kosoko, Obanikoro, Onilegbale, Olumegbọn, and Olorogun.
2. Purchase of Ẹnu—Owa by the Ọba of Lagos.
3. General.

**A. Ajose-Adeogun**
CHAIRMAN,
Ass. of Descendants of Lagos Chiefs and Lagos Aborigines Society.

**I. Isola Oluwa**
SECRETARY,
Ass. Descendants of Lagos Chiefs.

## Enyin Omo Ile Eko, E Fi Oju Si Iwe Yin

(O bẹrẹ loju ewe kẹfa)

Kinto pari ọrọ mi, emi yio fi orin kekere yi da yin laraya, orin na ni a ma nkọ nigbati mo wa nile ẹkọ, orin na lọ bayi pe:
Ọmọ ile-iwe ẹ ye sa ẹ ye sa, ẹ ye sa, o. Isansa jẹ ohun to buru, Iwe jẹ ohun ti o dara, ẹ fi ara balẹ ki ẹ kawe yin, ẹ farabalẹ ki ẹ mọ iwe yin, ọmọ ile-iwe ẹ ye sa o.

Mo ro pe gbogbo yin ni orin na dunmọ, ti ẹ si mba mi kọ bi ẹ ti nkawe yin, nitorina mo bẹ gbogbo ẹnyin ọmọde ile ẹkọ ki ẹ fi ara balẹ kawe yin, ẹ ye sa, nitori iwe jẹ ohun ti o dara.

Ẹ fi oju si, ẹ lọ ni suru, ẹ maṣe kanju jaiye, bopẹ titi ogun ọdun mbọ wa ku ọla, ọdun mewa ki ṣe titi lọ lailai, Oluwa yio ranwa lọwọ, ko ni jẹki a pade agbako o, ọpọlọ wa ko ni daru, ẹ fi oju si ẹkọ yin o.

Lakotan ọrọ mi, mo bẹ ẹnyin obi wa, ẹ maa ṣe ohun ti e ba ri pe o tọ ti o si yẹ lati ṣe fun awọn ọmọ yin, ohun ti ẹ ba si ri pe wọn bere, ẹ maa fun wọn, nidi eyi, ori wọn yio fi ma wu si iwe wọn, ki ẹ si ma ba wọn sọrọ iṣiti nigbakugba, Oluwa yio wa pẹlu wa o.

## Egbe Omo Ilorin Ma Tun De O!

Gẹgẹbi Iwe to jade ninu iwe "Eleti Ọfẹ" ti Saturday 7/4/62 wipe Ẹgbẹ Ọmọ Ilọrin ni Mushin koiti fidi mulẹ, irọ patapata ni ọrọ yi jasi. Bi ko ba jẹ bẹ, awa fẹmọ ẹniti o lọ si ọdọ baba Ẹgbẹ ni Abẹokuta Street, Mushin, ati orukọ baba ẹgbẹ ti ẹ lọ si ọdọ rẹ. Lẹhinna a fẹ mọ orukọ awọn to lọ si ọdọ alaga ni Paul Okuntọla Street, Mushin ati orukọ alaga na, to ba jẹ wipe ododo ni ọrọ ti ẹ sọ yi, eyi toyẹ nipe kari orukọ ẹniti o kọwe yi ati Number ile to ngbe.

Irọ patapata nipe, Ẹgbẹ na koiti fidi mulẹ, nitori pe awa Ẹgbẹ yi fidi mulẹ gidigidi. Nipa pe ani ifọwọsowọpọ pẹlu ẹnikẹni ti o ba wa ni abẹ aṣẹ Ọba wa ni Ilọrin, gbogbo oko Ilọrin, ti ti o fi de Bussa.

Lẹhi neyi, a si u aṣẹ eyiti o fi ọkọn wa balẹ gba, lati ọdọ Ijọba Apapọṣe (Federation of Nigeria) wipe ẹnikẹni ko gbọdọ jẹ orukọ na mọ. Bi ko basi da ọ loju, Iwọ na le fi han aiye pe iwọ njẹ Ẹgbẹ Ọmọ Ilọrin lẹhin ti wa yi, ki a si ri ka ninu iwe pẹlu orukọ akọwe ẹgbẹ na.

ẸGBẸ ỌMỌ ILỌRIN OF NIGERIA
REGISTERED N0. 92434.
HEAD OFFICE, ODI-OLOWO.
MUSHIN

Hadji A.W. Anifowoṣe,
Akọwe Gbogbo-gbo
Mushin.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370; Olotu L. A. OJO, 12 Inabere Street, Lagos.